YOURBA

Òbí/Alágbàtọ́ Ọ̀wọ́n:

Inú wa dùn pé ìwọ àti ẹbí rẹ jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ àyíká ńlá wa, níbití a ti ń sọ ju ọgọ́rùún èdè lọ báyìí. Ilé Ìwé Gbogbogbò Prince William County farajì fún fífún gbogbo ọmọ ilé-ìwé ní Ẹ̀kọ́ Ti Àgbáláayé. Nítorí ìbáṣepọ̀ ẹbí ṣe kókó ní ìlànà náà, inú wa dùn láti fún ọ ní àwọn ìwífún pàtó kan láti ran gbogbo òbí àti alágbàtọ̀ lọ́wọ́ láti lóye àti láti kópa nínú ẹ̀kọ́ ọmọ wọn.

Gbogbo ohun èlò ilé-ìwé ni a pèsè ní èdè Gẹ̀ẹ́sì, ṣùgbọ́n, a máa ń túmọ̀ àwọn àkọsílẹ̀ àti ìwífún tó ṣe pàtàkì sí àwọn èdè tó wọ́pọ̀ jùlọ bí a ti ń bèrè ní àdúgbò wa.

Àwọn olùsọ ọ̀pọ̀ àwọn èdè le jẹ ànàfní láti ìwífún pàtàkì tí a ń ṣàfikún nígbàdégbà ní ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù ti Ilé-ìwé Gbogbogbò Prince William County àti ti ilé-ìwé kọ̀ọ̀kan. Gbogbo wọn ní irinṣẹ́ Atúmọ̀ èdè Google tó ṣe pàtàkì, tí ń fúnni ní òdíwọn èdè ju èdè 50 lọ. Àwọn èdè tí a túmọ̀ lórí kọ̀mpútà kìí ṣe déédé, ṣùgbọ́n síbẹ̀ ń pèsè àwọn ìtọ́kasí pàtàkì sí ìwífún ilé-ìwé. Tí o kò bá ní kọ̀mpútà ní ilé, o le lo ọ̀kan ní ibi ìpamọ́ ilé-ìwé gbogbogbò.

Ní pàtàkì jùlọ, Ìpín Ilé-ìwé ń pèsè ìràyésí àwọn aáyan ògbùfọ̀ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ láti ran àwọn olùsọ̀rọ̀ lọ́wọ́ ti ọ̀pọ̀ èdè ti láti lóye àkọsílẹ̀ tí o ní ìwífún pàtàkì nípa ẹ̀tọ́ ọmọ ilé-ìwé àti òbí, àwọn ojúṣe, ohun ti a ń retí, àti àwọn ọ̀rọ̀ míràn tó jọmọ́ lílọ ilé-ìwé àti àwọn ànfàní àti ìpèsè tí àwọn ọmọ ilé-ìwé le gbà. Àwọn aáyan ògbùfọ̀ lé ṣèrànwọ́ pẹ̀lú àpèjọ òbí nípa àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí láti ṣàrídájú pé ìkópa ẹnìkọ̀ọ̀kan ni a gbéjáde tí a sì lóye rẹ̀. Àwọn ìpèsè wọ̀nyí ni a ń ṣe lọ́fẹ̀ẹ́ sí àwọn ẹbí.

**Lo ọ̀kan nínú àwọn ìlànà wọ̀nyí nígbàtí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ pàtó.**

- Lórí ayélujára- lọ sí translations.pwcs.edu.
- Lójúkojú-ṣàbẹ̀wòsíilé-ìwéọmọrẹ. Kódàjúpéolùsọèdèrẹyóòwàlárọ̀ọ̀wọ́tó. Ṣùgbọ́nòǹṣìṣẹ́ kanyóò lo àlẹ̀mọ́ láti le ràn ọ́ lọ́wọ́.

DR. STEVEN L. WALTS
*Superintendent of Schools*

P.O. BOX 389, MANASSAS, VA 20108 • WWW.PWCS.EDU

Nígbogbo ọ̀nà, a bèrè ǹkan wọ̀nyí lọ́wọ́ rẹ:

- Orúkọ rẹ àti ti ọmọrẹ;
- Ilé-ìwé ọmọ rẹ, ipele tówà, orúkọ olùkọ̀;
- Ẹnìkọ̀ọ̀kan (nípa orúkọ tàbí iṣẹ́) tí o fẹ́ básọ̀rọ̀, àti àkórí ìjíròrò; àti
- Nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ náà àti àkókò tí a le kànsí ọ dáradára.

Tí ọmọ rẹ bá mú ìfiránṣẹ́ kan wá ilé láti ilé-ìwé tí ń sọ nípa ìpàdé; tàbí o fẹ́ láti ṣètò ìjíròrò kan pẹ̀lú olùkọ́ kan tàbí ọ̀gá ilé-ìwé míràn, lo àwọn liana lókè láti bèrè fún ògbufọ̀ kan láti ṣèrànwọ́ pẹ̀lú àwọn ìbánisọ̀rọ̀ pàtàkì wọ̀nyí. Ẹnìkan yóò kàn ọ́ lára láìpẹ́.

Ìkóparẹ le mú ìyàtọ̀ dáradára wá nínú ẹ̀kọ́ ọmọ rẹ, àwa náà sì ṣetán láti ṣèrànwọ́ nípa jíjẹ́ kí àwọn ìpèsè wọ̀nyí wà fún ọ.A lérò pé lẹ́tà yìí sọ nípa ìfara-ẹni-jì ti Ilé-ìwé Gbogbogbò Prince William County fún ọ dáradára. Ó dá mi lójú pé wàá nípa nínú èròngbà wa fún gbogbo ọmọ ilé-ìwé láti gba Ẹ̀kọ Àgbáláayé.

Tìrẹ nítòótọ́,

Dr. Steven Walts
Olùdarí Àwọn Ilé-ìwé

*Nígbàtí o bá ń ṣàbẹ̀wò sí pwcs.edu, wá àwòrán àgbáyé aláwọ̀ láti ṣàwárí àwọn ojú-ewé pẹ̀lú ìwífún tí a ṣàpèjúwe nínú ìfiránṣẹ́ yìí.

